# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 546 TUESDAY MARCH 3, 1964 (2D)


## Obinrin Kan Pe Ọkọ rẹ L'ẹjọ Ikọsilẹ

ADO-EKITI:— Ni ọjọ Ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu kẹrindinlọgbọn oṣu keji ọdun yini, Ọmọge kan, Omidan Margaret Ojirongbe ẹni ọdun mẹrinlelogun o nṣiṣẹ olukọ pe ọkọ rẹ Afẹsọna l'ẹjọ ninu ile ẹjọ giga Ado-Ekiti fun iba adehun igbeyawo jẹ.

Omidan Margaret Ojurongbe ṣe alaye fun Ile ẹjọ pe, ọgbẹni Owoẹyẹ wa ba on ninu ọdun 1960 pe, on fẹ ki on di iyawo on, on si ti da lohun wipe, "Koburu, on na yio fẹ ẹ."

Omidan Margaret tun ṣe alaye siwaju pe lati igbana ni on ti fi ọkan si i wipe, on ti ni ọkọ, ti awọn mejeji si jijọ nwa ara awọn lọ si ile lẹhin ti awọn ba ti jade ni ile-iwe nitoripe iṣẹ olukọ ni awọn mejeji nṣe.

O ni ṣugbọn nibiti awọn ti nṣe eleyi lọwọ ni on rii ni ojiji wipe ọgbẹni Owoẹyẹ fẹ iyawo miran Paulina laisọ fun on o ni Obinrin na si ti bi ọmọ kan fun un

Omidan Margaret ni on ti gba pe Owoẹyẹ ni on yio fẹ laiye ati lọrun nitoripe ko fẹ on mọ, on fẹ ki ile-ẹjọ ba on gba adajọ pọnun (£150) owo itanran lọwọ rẹ. O tun ṣe alaye pe lati ọjọ ti on ti ri wipe Owoẹyẹ ti fẹ iyawo miran ni alafia ati aifọkanbalẹ ti wa fun on

Adajọ yẹ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kejilelogun oṣu kẹta ọdun yi

## Alhaji Adegbenro Sọ Pe:

# ẸGBẸ AFẸNIFẸRE PẸLU ALAKUKỌ NI O MA A ṢE APAPỌ IJỌBA NAIJIRIA

ABA:— Alhaji Adegbenro, Aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinnlẹ Iwọ Orun Naijiria, ti i tun iṣe Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre sọ fun Ipade awọn Oniwe ironin ni ilu Aba ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kini oṣu yi wipe, ẹgbẹ Afẹnifẹre (A. G.) ati ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) ni yio jijọ ma a ṣe Apapọ Ijọba Naijiria lẹhin ibo atundi ti mbọ yi.

Alhaji Adegbenro lọsi Ipinlẹ Ila Orun Naijiria lati lọwo iru aye ti awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ wa ni Ipinlẹ na.

Irohin fi ye wa wipe, Alhaji Adegbenro mba gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre sọrọ wipe, ki awọn ọmọ ẹgbẹ na omura giri, ki nwọn oma si se bẹru si ohun yowu ti oba de ba wọn Alhaji na ni fun igba diẹ ni gbogbo rẹ, ki ise titi lai

Ninu ọrọ, Alhaji Adegbenro fi ye ipade awọn oniwe irohin wipe, ibo atundi si Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria ti nwọn o di yika igun mẹrẹrin orilẹ-ede Naijiria laipeyi ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ni yio ma a ṣe akoso Ijọba na

Alhaji na ni eto ti nlọ ni abẹlẹ nisisiyi, fun ẹgbẹ mejeji lati le papọ di ọkan ṣo ṣo, ki nwọn si jijọ ma pa irẹ sinu apo kanna ninu eto ipolowo ibo ti o mbọ yi.

O ni eleyi jẹ eto ti gbogbo awọn ara ilu nfẹ pe, ki ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ o jijọ ma a ṣepọ. O tun ṣe alaye siwaju pe, jakejado origun mẹrẹrin Naijiria gbe nsọ wipe aṣepọ ẹgbẹ mejeji yi ni awọn nfẹ.

Alhaji na wa ṣe alaye si i pe, bi awọn ẹgbẹ mejeji ba jijọ nṣe Ijọba, gbogbo awọn ọmọ awọn ti o ṣẹṣẹ njade ni Ile iwe nisisiyi, ni nwọn o ma a ri iṣẹ ṣe, bani awọn ti nwọn si ti da duro lẹnu iṣẹ ni awọn yio ri wipe, nwọn pada si ẹnu iṣẹ wọn kia-kia.



ALHAJI D. S. ADEGBENRO

Alhaji Adegbenro tun sọ fun awọn oniwe irohin pe, on mọ dajudaju pe ti ẹgbẹ mejeji lo ṣiṣẹ pọ, nwọ o ṣẹgun ninu ibo ti mbọ yi.

Otun sọ wipe, eto ti nlọ ni abẹlẹ lọwọ bayi lati ri wipe aṣepọ awọn ẹgbẹ mejeeji le yọri si rere.

### ETO IKANIA

Alhaji Adegbenro ni gbogbo awọn enia ti ọpọlọpọ ori wọn ba pe, ni nwọn o kọ ọrọ ti Oloye Akintola sọ, ti nwọn ko si si ni gbọ ọrọ, bi ko ṣe wipe ki nwọn o kọ eti ikun si i.

Alhaji na ni Ọrọ ti Oloye Akintọla sọ ki iṣe ọrọ ti awọn enia Ipinlẹ yi nfẹ tabi ohun ti o jẹ ero ọkan awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun.

Alhaji Adegbenro wa so pe, "Ṣe ẹnyin na mọ wipe, oye ti Oloye Akintọla wa bayi. ko gbọdọ sọ ohun ti yio mu awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (N P-C.) binu."

"Ẹniti o gbe ọmọri odo mi, iduro ko si, ko gbọdọ bẹrẹ."

Ni ipari Alhaji D.S Adegbenro sọ pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ko faramọ abayọri eto ikania ti o jade la pẹyi

O wa kesi gbogbo 'enia ti o wa ni Orilẹ-ede yi lati kọ abyọri eto ikania na, ki nwọn o si ṣe kọ ibi ara si i

WO OJU EWE KẸFA

# IWA AWAWI TO WA LA-RIN AWA ỌMỌ YORUBA

Otitọ de ọja o kuta lowolọwọ ni a nra eke, totoṣe bi. owe Ohun to fa sababi owe yi ni pe mo ti gbọ lẹnu ọpọ enia ti nwọn ti nkun, ti nwọn nṣe idaduro lori ohun gbogbo ti ko lọ dede lariu ẹkun ilẹ Yoruba loni ati pe ọpọ ninu awọn enia ti ro pe o yẹ ki nwọn ronu lati wadi nkan to yingin larin ilẹ yi. Nişe ni nwọn fi atamọ mọ atamọ.

**Lati ọwọ S. O. Jaiye**

Nwọn nfi i b a j ẹ ṣe ayọ, nwọn nfi ohun itiju ṣe gba-jumọ larin ara wọn.

Nwọn sọ ọti mimu di ohun igberaga. Nwọn nfi ẹru silẹ ti nwọn nfa apamọ awọn obinrin Olobinrin kiri aiye.

Ọrọ lo ko mo ro wa. ..i ṣe ifẹ mi lati lo ede aibọ-wọ fun awọn ti a ba npe ni aşaju ẹni nitori bọya ọjọ kan nbọ ti ẹyin yo di aku-kọ ti akukọ na yo si wulo fun orilẹ aiye.

Awawi to wa larin wa loni pọju ohun to ba wa gẹgẹ bi orilẹ ede Yoruba. Gbogbo wa ni o mọ wipe gbogbo nkan yingin larin wa.



Dọkita Majẹkodunmi

Awa si mọ wipe ko si orilẹ miran to le pari ọrọ na fun wa bi ko şe ki a fi ori kori ki a ba ọdọfin inu wa şe apero ọna ti ao fi tun ọna wa şe gẹgẹ bi iya kan.

Awọn ti aro pe nwọn je ẹlẹkọ pupọ, nwọn kọ lati wa ọna ododo ri lati pari ija yi.

Njẹ nwọ se eyi? Boya awọn miran le gba ọna miran to ro pe ija na le pari ki ọna na ku na.

Eyi ko sọ pe ki ama tun tẹ si ọna miran titi a o fi yanju ọrọ to wa larin wa. Eyi ko dara ki ama wo ki aye ati aiye ti o fi silẹ fun awọn ọmọ wa lẹhin ọla fi lọ s ọna ibajẹ.

Ti imọ ẹkọ giga ba jẹ ọgbọn ori ni ese ti awọn ẹlẹkọ wa oni yi ko ronu ọna ti nwọn yo fi gba lati ri wipe eto wa fun ipari ija na.



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

Ọkọ omi Yoruba wa ni agbami okun aiye loni yi. Ninu ọkọ yi ni awọn isu-ra wa ti alumọni kun ọkọ omi yi.

Şugbọn lai ro tẹlẹ ọkọ ti idi bọ ori yanrin şinşin. Awọn awa iyanrin wa ni-nu ọkọ yi, ohun ẹrọ to le şe iranlọwọ wa ninu ọkọ pẹlu

Bakanna awọn ti o le şe iranlọwọ wa ninu ọkọ yi.

Bayi ni gbogbo awọn enia to le şe iranlọwọ du-ro ti nwọn si nwo pẹlu ifi ọwọ lẹran.

Bawo ni ọkọ na şe le le-lo ?

Moro pe ohun to dara julọ ni ki gbogbo awọn to le şe iranlọwọ ninu ọkọ ni pe ki nwọn ti emi işọkan nwọn la kaka lọna kọna lati şe iranlọwọ fun igbala ọkọ yi eyi ni o le mu ki e o to wa ninu ọkọ na gu i lẹ ni alafia.

Lẹnu awọn ti a ro pe ọrọ ire iba wa ti ọrọ itunu ati ọrọ pẹlẹ iba wa lati mu edeaiyede de opin larin ilẹ yi.

Nwọn ko şe bẹ rara di-po eyi ọrọ alufasa, ọrọ ọtẹ ni nwọn yio ma sọ ja-de lẹnu bi alai nani ohun ibajẹ to wa nilẹ.

Ti enia ba ji larọ lati wo nkan to şẹlẹ ninu aiye ati bi ilọsiwaju ti nlọ si la-rin awọn orilẹ ede.

Dipo ti awa iba fi kọ ẹkọ ninu awọn wọnyi. Ki-ni awa nşe ?

Ohun ti mo şe akiyesi ju lọ ninu iwe irohin ilẹ Yo-ruba ni ki a ma şe ẹrẹkẹ ebu si ara ẹni, ki a ma pe ara eni ni orişirişi orukọ ti ko yẹ rara.

Owe Yoruba sọ pe, ti a ba fẹ mu ọbọ a ni lati da-bi ọbọ. Ki şe ki a ma bu ara ẹni lo le mu ija pari la rin ilẹ Yoruba.

Ki şe ọta ẹni ni a ni lati bẹru bikoşe ọrẹ ẹni to wa lokan aiya ẹni. Mo ri pe bi a ti nsa fun ọta, ni ọta ẹni nsa fun ni.

Nipa bayi alafo ti yio wa larin awọn ọta mejeji yi yio jinna si ara wọn pu-pọ tobẹ ti ọwọ ko fi ni le to ara wọn.

Nitori a ninu awọn ti a ro wipe ewu wa larin Yo-ruba loni yi ko to ti awọn ti nwọn joko ti nwọn nmu ti nwọn nieun pọ.

EDE ALUFANSA

Ninu awọn iwe Irohin ni ede Yoruba, mo saba ma şe alabapade awọn ede ti



ADESỌJI ADERẸMI

ko yẹ ki a ma lo si ara ẹni.

Bi ki a ma pe awọn kan ni Uku-Uku, keferi a t i Yanminrin ajẹsẹ diẹ. Iru awọn ede bayi ko mu irẹ-pọ wa larin awọn alabagbe ati aladugbo ẹni.

Nigbamiran a o ri pe ede ko ye awọn ti o ba npe ede na Nigbati a w a nkẹgan



Oloye S. L. Akintọla

wọn Ọlọrun si nbukun wọn nitori On lo da gbogbo wa.

Ti a ba fun wa ni ibukun WO OJU EWE KARUN



Ọgbẹni S. O. Jaiye

# IWE SI OLOTU

## Ẹfi Kun Bọọsi Awọn Ọmọ Ilewe

Olotu. Inu mi iba dun sẹsẹ ti ẹba le tẹ Iwe mi yi jade fun awọn Igbimọ ti o mu oju to bọọsi ilu Eko (Lagos Municipal Transport Service) lati ka.

Ohun ti ko dara ni lati ri wọn Ọmọ ilewe giga bi wọn ṣe sare dirọ mọ bọọsi larin Eko, nitoripe oti kun pipọ ju.

Oyẹ ki awọn Igbimọ na fi kun bọọsi na ki ọma ba si wahala ati ki wahala le dinku fun awọn mọ ilewe wọnyi.

Olotu modupẹ lọwọ yin fun aye ti ẹfi gba mi. Ọwọ yin yi ma roke.

Emi ni,
BABA TAJU
Eko.

## Kini fa ira eyi ?

Olotu, Ẹjọwọ ẹ gba mi laye lati le fi iwe mi yi ke si alakoso ilera ti Ijọba Apapọ Naijiria Oloye Dọkita Majẹkodunmi l o r i Iwa awọn oṣiṣẹ Ilewosan Unifasiti ni Idi araba.

Ha!, bawo lo ti jẹ ti ofi le jẹ pe ti enia ba farapa ti asi sare gbe lọ si ibẹ, inira ni yio jẹ fun awọn oṣiṣẹ yi lati le tete da wọn lohun lasiko.

Larin ọsẹ yi ni, A gbe Iyaagba kan lọ si ilewosan na, pẹlu ọmọde kan ti wọn fara pa a ni dede agogo mẹwa arọ, ki nwọn to le da wọu lohun pẹlu inira o to agogo marun irọlẹ. Iru Iwa bayi ko ba oju mu rara osi fẹ amojuto gidigidi.

Nipari ọrọ mi, mo fẹ ki Ijọba Apapọ ṣe Ayẹwo lori Iṣẹ awọn ti o nṣiṣẹ ni Unifasiti yi nitori ọjọ Iwaju.

Olotu Ajinde ara yio ma jẹ o.

Emi ni
JOSEPH OLONADE
Yaba.

## Ẹmojuto Awọn kero Ogunpa

Olotu, Mo fẹ ki ẹgba mi laye lati le ba awọn Igbimọ ti moju to ilu Ibadan (Ibadan District Council) sọrọ lori iwa kiwa ti awọn agbero Ogunpa nhu fun awọn ero ti o ba fẹ wọ mọto.

Iwa ti oburu ju ni a w ọ n agbero yi nhu, Ọpọlọpọ lo saba padanu ẹru wọn ti osijẹ pe ofo nla ni o ṣe wọn lori pe wọn fẹ mọto.

Afẹ ki awọn Igbimọ yi tete nmojuto ọrọ yi.

Mo dupẹ pipọ lọwọ yin Olotu.

Emi ni
LAMIDI ỌLAỌRẸ
Ibadan.

## Ariwo Awọn Onimọto Pọju

Olotu, ayọ ni iba jẹ fun mi ti ẹ ba le jẹ ki iwe mi yi jade ninu iwe yin aladun yi.

Pataki ọrọ mi ni lori awọn oni mọto ti Ijọba ti paṣẹ le lori pe ki nwọn maṣe ma fi fere mọto wọn pariwo mọ loju titi.

Otitọ ni ofin yi ti Ijọba ṣe, ọpọ lọpọ enia ni awọn onimọto ti nfi fere mọto yi jalaya ti nwọn fi nkọ lu mọto.

Bẹsi ni awọn ọmọde ti o ba gbọ fere yi lojiji ti wọn yio fi sa rebọ si ẹnu mẹto.

Nitori iru eyi. mo fẹ ki awọn Ọlọpa mura lati gbogun ti iwa buburu yi larin Eko.

Olotu, mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ fun mi lati le ṣe alaye ọrọ na. Ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o Amin.

Emi ni,
MAKINDE OYEWỌLE,
Eko

## Ebute Ọkọ Apapa nfẹ Atibaba

Oloto, Mo nfi Iwe mi yi kesi awọn Igbimọ ti nmojuto Ebute, Eko ati Apapa (Nigeria Port Authority) lati le kọ atibata fun awọn ero ti nwọ ọkọ Katilini ati Apapa si Eko,

Asiko Orun ni awa yi, enia ti oba duro fun nkan bi ogun iṣẹju lati wọ ọkọ katilini yi yio ri ohun ti orun yio foju on ri, bẹsi ni ti ojo bade, nkan bukuru ni eyisi jẹ.

Owo sa ni awọn ti nwọ ọkọ yi san.

O to asiko fun awọn igbimọ lati ṣe ẹtọ nwọn

Emi ni
GABRIEL OKERE
Apapa.


## Akiyesi

Anikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oṣi wa laaiye tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Iṣẹdalẹ Yoruba, ki oluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe jẹki agbagbe itan Iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU



## ỌJA TITUN FUN TITA

1. Iwe Ilana fun Iyanrin, iwosan ati etutu ṣiṣe 20/-
2. Iwe Egbogi Ajẹbidan awogbarun 25/-
3. Iwe Afọṣẹ iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm iṣẹgun awọn Ajẹ 4/-
4. Gbedegbẹyọ Hausa, Ibo, Oyinbo ati Yoruba/-
5. Iwe itumọ Ami Ara ati etutu ṣiṣe 4/-6d
6. Iwe itumọ Ala lati ọwọ Josẹfu Alala. 7/6d

Iwe Afinimọna Mẹkka ati awọn orişirişi iwa Yoruba.

Gbiyanju lati bọ ajaga awọn Oṣo, Ajẹ ati awọn ẹni ibi ile aiye silẹ nipa lilo Iwe Adura, Iwe Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Iṣẹgun Ajẹ.

PẸLU AWỌN ERO IJA RẸ BI:

Holy Candle, Turari iṣẹgun Ajẹ. Apapọ owo ẹ jẹ 20/- A o fi lilo wọn ranṣẹ si ọ pẹlu; ti o ba fẹ o le wa fun ara rẹ.

MANAGER:
N2/99, Shittu Street
Ibadan.



## KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa na le jẹri wipe Ojulowo hauhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS wa na nio ni Gold Coast (Ankara Ghana)pẹlu, meji rẹ ko si ninu oqgbo orişirişi Egbogi kakiri Ilu Naijiria,




### Irohin Kakiri Igboro Ilu

Bẹ na ni ẹwẹ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti owa lẹnu gbogbo enia mọde t'agba ni asiko yi ti nwọn si fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn ọpọn Egbogi Jama i olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dọkita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bio ti lagbara to ati o jẹ Ojulowo giriki ati atamata se fun awọn "JẸDIJẸDI" bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni Iwọn le tun fi ọwọ sọya tabi ṣeileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi Iju, tabi Igẹ ṣiṣe, tabi aiko riigbọnṣẹ dede, Inu rirun nigbakugba ti ni woiwo, Ẹsanri, ẹhin didun, Oju sisan, tabi aiko riran kedere k'odo buruku lara, Osiinu Onigbameji ati orişirişi arun miran gbogbo pata "Wipe" nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo Egbogi LEOPILLS nitoripe o si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọ di ọtun p [illegible]

IṢE IRANTI PE ALAFIA L'OGUN ỌRỌ, IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9d)

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS: Igo nla şile mẹfa abọ (6/6) pere ni Igo kekere şile mẹta abọ (3/6) pere ni

Bere Ojulowo Egbogi miran fun orişirişi Amọdi ti o a fẹ ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos,
Phone: 22878 Nigeria (Oja ita Faji)

(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street Yaba

# Ọlọla Ọlanrewaju Pe Ẹjọ Ibanil'orukọjẹ

EKO:— Alakoso awọn Ọlọpa Ijọba Apapọ, ilẹ Naijiria Ọgbẹni Moses Ọlanrewaju ni a gbọ pe o pe Ọgbẹni Kọlawọle Balogun ati Sadiku Akande lẹjọ ibanilorukọjẹ ni Ile ẹjọ Giga ni Eko ni ọjọ Ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi.

Onirohin wa fi'ye wa pe ninu ẹjọ Ọgbẹni Ọlanrewaju ti o ti bere fun owo ọkẹ marun pọnun fun orukọ rẹ ti nwọn bajẹ ninu iwe kan ti awọn meejeji yi tẹ ninu oṣu kẹrin ọdun 1963.


Ọgbẹni M. A. Ọlanrewaju
Minista Alamojuto Eto Awọn Ọlọpa

Adajọ agba ti kotu giga yi tun sun gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kẹsan oṣu kẹta ọdun yi.

Bi ẹjọ na ba ṣe nlọ, ẹo tun ma gbọ o.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIES Jan. 20 - Feb. 18) Ṣe pẹlẹ loni ti o ba jẹ ẹniti o nwa mọto tabi o nwọ mọto lọ si ibikan nitori jamba.

PISCES (Feb. 19 - March 20) Ṣọra pẹlu ọrọ ibinu loni, ki o si ma wo ẹlomiran ṣe iṣẹ rẹ ẹnikan ki gbọn tan.

ARIES (March 21–April 19) Ọrẹ rẹ yio ran ọ lọwọ lati sọ okeiṣoro rẹ ti o ti wa fun ọ lati ọjọ pipẹ di pẹtẹlẹ loni ti o ba gba imọran.

TAURUS (April 20–May 20) O ṣe alabapade awọn enia kan ti o ṣe iranlọwọ fun ọ loni.

GEMINI (May 21 - June 10) Ọwọ rẹ ko ni le tẹ lohun kan ti o nfẹ loni, ṣugbọn ni suru diẹ si i.

CANCER (June 21 – July 20) Iwọ yio ṣe alabapade awọn enia kan ti o ti ri pẹ, gba imọran ti nwọn ba fun ọ, ti o ba nfẹ ilọsiwaju ara rẹ.

LEO (July 21–Aug. 22) Orire wa fun ọ, loni, o si le yanju gbogbo idiwọ ti o ti wa niwaju rẹ.

VIRGO (Aug. 23 – Sept. 22) Nitori ọrọ ibinu kan ti o wa niwaju rẹ loni, ṣọra pẹlu ode ilọkulọ ati ọrọ ariyanjiyan.

LIBRA (Sept 23 Oct 22) Ti o ba ni igbagbọ si ara rẹ okeiṣoro idiwọ ko si fun ọ loni.

SCORPIO (Oct 23—Nov 21) Gbiyanju lati ṣe ibẹwo awọn enia rẹ loni, bakanna ni ọjọ oni si tun dara fun ọ lati lọ si irinajo.

SAGITTARIUS (Nov 22—Dec 21) Maa fi ọrọ lọ enia ki o si ma gba imọran ki o ma ba ṣiwahu loni.

CAPRICORN (Dec 22—Jan 19, Maṣe fi eti si gbogbo ọrọ isọkusọ ti oba ngbọ loni, si ṣọra pẹlu afa mako nitoripe ara rẹ nfẹ isimi.


## A TUN GBE DE!

Iwe Adura pataki fun Arisiki ati iṣẹgun lori ohun gbogbo lati ilẹ Misirat, 2/6 Adura akanṣe ,ati aperẹ ile aiye 2/- Ajọmọ-isin Ojiṣẹnla Mahammed 2/- Iwe Itumọ Ala ati Adura Ala ibanujẹ 4/6

RANṢẸ TIRẸ SI:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue Lagos Nigeria
(Leti ọja Jankara)



BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**IWE Igbeyawo**

TETE KOWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE
MODUPE PRINTING PRESS
16, Bamgbose Street, P. O Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyato


# E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ


## PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidgidi fun "Ipare" ti awọn alliera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba Alefọ. Egbo ẹsẹ oriṣiriṣi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adasin ọ egbo, ekusẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara si Akọ Inarun ati oriṣiriṣi arun "ARA" miran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi titun ti awọn ara Ilu Tatan ulu ṣe ti wọn npe ni "PAYAL" wo larin ọjọ meta 'wọ na yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu Egbogi ipara yi ki ṣe awọn robirobi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si ṣiṣe ye meji ninu lo je eleyi si yatọ patapata si awọn egẹrẹmiti adimowọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni agbereko gbogbo pẹlu. Orisi meji rẹ lo wa. Kekere ati nla.

Bere egbogi ajebina Payal yi ni ṣọbu wa...

Waterloon Medicine Stores
8, Palmchurch Street. Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

NIGERIA MEDICINE STORES
Tinubu Street, Lagos, Phone:- 20278

# Ọmọ Kan Lu Baba Rẹ Pa Bamubamu

OPOBO:- Ọrọ nla lo sẹlẹ larin ilu Opobo ni ọsẹ ti okọja yi nigbati Baba kan ati ọmọ rẹ wọja kadi; ti ọmọ da Baba rẹ mọlẹ wẹrẹ ni Baba ba sẹ be ku.

Onirohin wa lati ilu Opobo fi ye wa pe ọmọkunrin yi, se iwadi lọdọ Baba rẹ Eno Akpan idi rẹ ti ko fi le ran on lọsi lewe.

Bi Baba yi ti nse alaye fun ọmọ rẹ, were ọmọ yi ni alaye Baba on kọtẹ un lọrun ni ija bade.

Onirohin wa tun fi kun bi ọmọde kunrin yi ti da Baba rẹ mọlẹ ni ẹjẹ bẹrẹ si jade lati ẹnu rẹ.

Ọrọ na wa di pe awọn aladugbo pẹsẹ, ti wọn si gbiyanju lati gbe Baba na lọ si ogba ọlọpa.

Agbọ pe awọn ọlọpa ti da ọmọdekunrin yi duro.

# Iwa Awawi Larin awọn Ọmọ Yoruba

(Lati oju ewe kej)

ti a ko ba mọ lo daju ti a ba gba ibukun lọwọ ẹni ko ma buru.

Ọpọ ninu ẹnyin ti ẹ nbu awọn kan loni ti ẹ si npẹgan wa loti wa laye kan ri ti ko nanni awọn iya ọmọ iya wọn bi ko ṣe ki o ma fẹla lori iṣẹ oyinbo ti ṣe iṣẹ ọwọ baba ẹnikan.

OMINIRA

Mo tilẹ ro wipe ojẹ ibukun nla pataki kan pe awọn ọmọ to wa labẹ ẹni nipa ipimọra, iṣẹaraẹni nwọn wa di enia ati orilẹ ede nla lẹhin ọla.

Ẹjẹ ki a kọju si otitọ nitori otitọ ni yo sọ wa di ominira. Nigbati iwọ onisọkusọ ṣe tea ti o fi ẹyọ ṣugar kan si laisi wara ti o ngbe mu wipe tea ni iwọ nmu, pẹlu ọmọ rẹ ti ẹ nfẹla kẹ ẹ.

Lẹhin eyi owa fun ọmọdọ rẹ ni kobọ meji wipe ki o ra ẹwa adalu kobọ ogi kọbọ ki o si pomu laironu, ṣe onjẹ atata ni o nfun ọmọ jẹ? O ko mọ pe ọmọ ọmọ to mu ẹko pelu ẹwa yo di alagbara ju ọmọ rẹ lo. Bayi ni ọpọ ẹnyin ọmọ Yoruba nṣe ni ọjọ wọn ni.

ARA OKE

Ṣugbọn awọn ọmọ na di alagbara ati elero lori. Awọn Ọmọ Yoruba to wa ni ilẹ nyin kọ ni e npe ni ara-oke danasungbo.

Loni wo awọn ọmọ iya nyin igba ini ti e nfun loruko larinnyin. O di loni ẹ wa nkun bi ologbo to jaja ekute pa.

Oluwa sọ pe gbogbo nkan wọnyi ni ẹ nṣe ti mo si dakẹ ṣugbọn Emi Oluwa yio bere wọn lọwọ nyin. Ọrọ yi dun mi pupọ fun aironu ẹnyin enia.

Lana ọmọ lọ rẹ ngba ilẹ fun ẹ. Ṣugbọn loni iwọ wa ninu bata rẹ o tun njirẹbẹ nwaju rẹ. Iwọ ko ro ri?

Paripari gbogbo ọrọ yi nipe ko si ẹniti oburu julọ ninu aiye ti ko mọ pe on buru, bakanna ẹniti o subu lulẹ ti o ro pe on nrin. Ẹniti etan wọ lẹwu to ro pe olododo ni on. Ohun ti mo ni sọ nipe ki orilẹ ede Yoruba ronu. Nijeran-Yoruba ni Youth Movement, nijeta Yoruba ni Oduduwa ati Action Group lana UPP ati Ọlọfin!!! Loni nkọ? Anrapala ninu ete ati ero miran. Ijo wo ni Yoruba yo wa sọkan? Odi ọwọ nyin osi di ọwọ irosupiwada ọkan. Ẹjẹki afi awawi ofo silẹ.

Odi gba o.


## EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI



**"CYCLEVEN"**

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ o si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe "omusu tabi Iho idi" enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkuarin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọw rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro be rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVFN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kan ki o si danwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi ti o wa nigboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)



## Akiyesi Pataki

A nfẹ Aşoju ni awọn ilu wọnyi, Ọtta Abẹokuta, Ibadan, Ilugun, Olodo, Agbọwa,-Iko si Ikorodu, Ọyọ, Awẹ, Ilesha, Ẹde, Ikirun, Iwo Shaki Işẹyin, Tede, Oke-Amu, Iganna, Omu-Aran Ilorin Ajaşşẹ-Ipo, Ifọ, Abalabi, Idọgọ.

Kọwe si

Circulation Manager.
16, Gbamgbose Street,
Lagos.



## Kere O! Akiyesi Pataki

Antoin Tablets! Antoin Tablets!

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ Ẹku afojuba Egbogi pataki ti aşe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Onişegun (Specialists) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ Arun wọnyi:—

IGBONA:- Eyi jẹ arun ti o sọpọ ni ode isisiyi papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORIFIFO, TULU, LUKULUKU OTUTU IGBAIYA, ARA RIRO ati OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKOKORO lọwọ danwo Ajẹbidan ni ogun yi. Irohin ko lo Afojuba Bere iwe ti o o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta egbogi na fun yin. Odaju hanwun. Ẹ o ri iṣẹ rẹ lẹhin işeju medogun ti ẹ lo. Bere lọwọ awọn Onişegun adugbo rẹ.

*Distributors*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
Phone: 2374
26, Bishop Street
LAGOS

# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 546 TUESDAY, MARCH 3, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe meieji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Ironin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akiutọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16' BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

OLOTU

# Ẹgba Mẹta Enia Ni Yio Di Alairi Ile Gbe Ma Ni 1lu Eko

EKO:— Ẹgbaata enia ti ogbe adugbo mejila ti Ijọba Apapọ ti paṣẹ pe nwọn yio gba lati le fi ṣe ọna si lati le fi kọ Afara Kereni keji fun un ilu Eko ni agbọ pe nwọn ko ti ri ibi ti Ijọba yio fi wọn wọ si.

Ọrọ yi ti da ẹru ba gbogbo awọn ti ngbe adugbo wọn yi, nitori pe ohun iṣoro ni yio jẹ fun wọn lati le wa ibugbe miran fun ara wọn.

Ninu ipade kan ti awọn ti ọrọ yi kan ṣe ni ile ẹkọ Ahmadiyya ti Ẹlẹgbata ni Eko lana ni Irohin fi ye wa pe awọn ti ongbe Apọngbọn Alakoro ati Marina jumọ gbero lati lati yan igbimọ kan ti yio ma ja a fun wọn lori ọrọ yi.

Irohin na tun fi ye wa pe, awọn aladugbo yi ti gbero lati fi ọrọ wọn wọn han, Olotu Ijọba Apapọ. Ipade tun pinu lati le ran ikọ lọ si ọdọ alakoso ti mojuto Eko Alhaji Yar Adua.

Nwọn si ṣetan lati le bere pe ki ijọba fun igbimọ ti o mojuto idagbasoke ilu Eko (L.E.D.B ) lati le pese ibugbe miran tabi ilẹ miran fun gbogbo awọn ti a ba le kuro lori ilẹ wọn.

Ipade na fi han pe awọn ko tako Ijọba lori pe ki wọn ma ṣe kọ afara na a. Ṣugbọn ẹtọ awọn ni lati bere fun ibugbe miran ki awọn ma ba di asunta.

Nigbati onirohin wa lọ lati wadi lọwọ ọkan ninu awọn oṣiṣẹ Igbimọ ti mojuto Idagbasoke Eko (L.E.D.B ) o sọ wipe koi ti yẹ lati le sọrọ lori rẹ nisinyi. O so pe, ọrọ na si ku diẹ fun sisọ.


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHALẸT** Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu 'ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ọjulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu s Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Ojuṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọiba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ininu ẹjẹ ara rẹ patapata yio isi fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu

Ṣa dan igo rẹ kan wo n iwọ yio si ma a rohin rẹ fura omiran pẹlu.

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja (Ita Faji)

NIGERIA MEDICINE STORES
Tinubu Street, Lagos, Phone:- 20278


### AJUMỌSEPỌ ẸGBE AFẸNIFẸRE PẸLU ẸGBẸ ALAKUKỌ

Lati Oju Ewe Kini

Ikede ẹgbẹ na ti o tun jade ni Ibadan lana ti kesi Alhaji Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria pe "ki otete sọ fun aiye gbọ, bi awọn Akọwe ti owa nidi eto ikowe ikania ko ba ba ara wọn ja ni ainiye igba lari iwe ti owa lati Ipinlẹ Ariwa nigbati awọn eniana ko ri Ojutu ọran na?"

Ikede ẹgbẹ Afenifẹre wa pari bayi pe, "Bi Alhaji Abubakar ba kọ ti ko sọ Ohunkohun lesi ọrọ yi, ẹgbẹ Afẹnifẹre yio bẹrẹ si tu rẹkẹrẹkẹ ọrọ si ita laipẹ yi ninu awọn ohun ti oti sẹlẹ, ki awọn enia ole mọ ohun ti oti nlọ ni abẹlẹ.


THE WATCH WITH PERSONAL TOUCH
WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

Réf. N° 55. PHOTO

Free illustrated catalogue on demand



A Wonderful 15 Jewel lever shock protected movement, non magnetic, unbreakable mainspring ROLLED GOLD waterproof case and stainless steel back with your name engraved.

Beautiful diamond polish raised figures, luminous and YOUR PHOTO reproduced IN COLOR on metal dial

PRICE £ 5.

HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque

WINDSOR
19, Avenue de Lérins - Cannes, France



Printed and Published by Mooupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495 Phone 21985
Editor : TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga Yaba Lagos 3/3/64